**Wanted**
One Editor
Apply in Person to:-
IROHIN IMỌLẸ
16, BAMGBOSE
STREET, LAGOS.


# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.


**Owe**

Lati Ọwọ I. Akinliy;

(1) Eniti a baje lọdun to koja ko si mọ ẹni aiye bari ni aiye mbẹ jẹ.

(2) Gba ẹkara, gba dundun lo jẹki ọmọ de mọ oju ẹni.

VOL. V No. 313 MONDAY JANUARY 22 — JANUARY 28 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# Egungun pa Egungun, Adiẹ njẹ fun ara wọn Koleriwọ Ọlọpa mu awọn enia mẹfa

LAFIAJI:- IROHIN TI A GBỌ NI WIPE NI ỌJỌ 26th OṢU DECEMBER 1961 NI A GBỌ WIPE IJA KAN BẸ SILẸ LARIN AWỌN EGUNGUN MEJI TOBẸ TI AGAN BẸ LARIN WỌN, A SI GBỌ PE ONILU WỌN BẸRẸ SI FI ILU RẸ SỌRỌ BAYI PE, ADIẸ NJẸ FUN ARA WỌN KOLERIWỌ.

Nigbati awọn Egungun gbọ ohun ti ilu yi nwi, ori wọn yi, nwọn nna ara wọn ni ẹgba awọn Elegungun na ṣe ara wọn ni jamba.

Enia mẹta lo fi ara gbọgbẹ ninu ija na ti o jẹ eyiti o le, Orukọ wọn ni Iṣọla Joseph, Robinson Eboh ati Salisu Jimọh. A gbọ pe awọn mẹtẹta nwọn ṣe ara wọn leṣe, tobẹ gẹ ti nwọn ni lati gbe wọn lọ si ile Iwosan Orthoepadic

Eyiti a npe ni Iṣhọla ti Ṣalaisi, eyiti o njẹ Robinson Eboh na ti ta feru nipa a yafi ey ti o njẹ Salisu Jimọh ti iṣe ọmọ ỊImale nikan lo ye, ti o si de ile rẹ ni alafia.

Awọn enia ti Ọlọpa mu pẹlu awọn enia mẹta ti a darukọ ni, Latifu Agbabiaka, Mufutau Arẹmu, Bright Omọraji, Amusa Gasper Joseph Babatunde ati Kayọde Willoughby. Igbẹjọ di ọjọ 26th Jan 1962.

## Tanki Petro jalule kuro lori Alaru re lona Apapa

APAPA: A gbọ irohin wipe lẹhin ti mọto nla kan ti lọ gba epo Mọto kun inu Tanki rẹ, o murs lati kọri si ọna ilu Oke. Gẹrẹ ti o kuro nibiti o gbe ti ngba epo Mọto, ni Tanki nla ti nwọn nrọ epo mọto sinu rẹ ba re bọ silẹ kuro lori Alaru rẹ.

Ki a to ṣẹju pẹ, awọn Panapana ti de ibẹ, nigbayi ni gbogbo awọn Mọto ti o nkọja lọ si Apapa ko ri ọna lọ mọ, bẹni awọn ti o mbọ ko ri ọna gba mọ.

Nigbayi ni ooruu epo Mọto wa gbojikan awọn Panapana ṣe ikilọ pe ẹnikẹni kogbọ dọ Ṣana ni agbegbe ibiti mọto na ṣubu si.

Nitori idi eyi ko jẹki awọn Pana pana le kuro nibẹ, nwọn nṣe ikilọ fun awọn Mọto ti o lọ ati eyiti o mbọ.

HU-U-HAHA! MO YỌ FUN Ẹ, MO YỌ FARA MI HU-U-HAHA

Nigbati akoko ti wọn ba fẹ ṣe ere Adamu-Orisa ba nsunmọ etile bayi, a ma nsaba gbọ iru orin bayi wipe, Ẹyọ ti ko ba gbawe, ko gbọdọ d'Agodo, Agodo ni'ga Ẹyọ. Hu-u-haha! ẹmi a b'eju pa a ẹmi a boju wo o, ẹmi a boju bọmọ lẹru bi orisa. Alẹlẹ we imalẹ, Okunkun ima kun birimu-birimu. Ẹniti ko ba mọ iṣe, okunkun ko ma da oṣupa loro. emi ni mọdẹ iraye, hu-u-haha.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJI

## Omo ile Naijiria kan bimo ni Ilu Oyinbo



Ọgbẹni O. Eromọsẹle ati iyawo rẹ lo bimọ obinrin kan si ilu Oyinbo, nwọn si sọ ọmọ na ni orukọ yi. Ọmọṣagba Abieyuwa Ṣineda, Baba ọmọde na ni olori Oniwe Irohin fun Asoju ilẹ Naijiria ni ilu Oyinbo. Awọn ti a nwo ni iduro nwọnyi ni lati ọwọ osi Omidan Elisabeti Etuk, on ni Aboyun ti o wewu ojo lẹrun ọkunrin ti o tele ni Ọgbẹni S. O. Okonofua, Alufa Ẹni ọwọ Booki on lo sami fun ọmọ ti o si fun ni orukọ Chineda Ọkunrin ti o wọ ẹwu dudu ati obinrin ti o wọ ẹwu funfun ni Iya ati Baba to bi ọmọ na, obinrin Oyinbo ti o gbẹhin ni Omidan Maya Foale.

# ỌRỌ OLOTU

LET US RESPECT OUR NATIONAL ANTHEM

## E jeki a bowo fun orin Orile-ede wa

Ko ni dun to, bẹ si ni ko ni dara to bi awa Oniwe Irohin Imọlẹ ba ri ohun kan ti ko dara ti awọn enia nṣe tabi ti awọn alaṣẹ Naijiria ba nhu ni iwa, ti a ko ba si tete yara kigbe wọn sita, ki wọn le mọ pe nkan na ko dara to, tabi o ku diẹ ki o to, nitoripe iṣẹ wa ni lati ṣe bẹ. Ohun na ni o fa ti a ṣe lẹ ba ẹnyin enia Naijiria sọrọ nipa orin Orilẹ-ede wa, bi a ba wo lọ ni nkan bi Ọdun merin tabi ju bẹ lọ sẹhin nigbati a si mbẹ ni abẹ asia Gẹsi ti a ko ti gba Ominira a o ri pe, nibikibi ti o wu ki awọn Oyinbo Gẹsi wa, ti won ba ti gbọ orin "Ki Ọlọrun da Ọba si" eyiti nṣe orin Orilẹ ede ti wọn, nṣe ni wọn yio duro tọwọtọwọ titi orin na yio fi tan, papa ni ilẹ ibiti a gbe nlọ wo iran ere alẹ (Cinema) nigbati wọn ba ti pari ere na, orin yi ni wọn ma nkọ gbẹhin gbogbo igbati wọn ba si nkọ orin yi lọwọ nṣe ni awọn Oyinbo ma wa ni duro titi orin na yio fi de opin, eyi si fi han gbangba pe wọn bọwọ fun orin Orilẹ ede wọn ni yẹn.

Ṣugbọn losiko ti a wa ti gba Ominira yi, a si ti ni orin Orilẹ-ede ti wa, ṣugbọn a ko bọwọ fun orin na rara, eyi si jẹ ohun ti o bu ilu wa ku. Ẹni to ba bini ni a jọ, eniti o ba si tọni ni a wo, nitorina awọn Gẹsi tọ wa, ṣugbọn a ko mu iwa wọn, ti o ba ṣe wipe, a tẹle iwa wọn ni, o yẹ ki a wa na ma bọwọ fun orin Orilẹ ede wa gẹgẹ bi awọn ti o tọ wa tiṣe tẹlẹ ri, ibikibi to wu ki a wa, ti a ba ti gbọ orin yi, o yẹ ki a duro tọwọtọwọ titi wọn yio fi kọ orin na delẹ. Eleyi yio fi han wipe a ti di Ominira ara wa ni totọ. Ki ṣe pe orin Orilẹ ede wa yi wa lasan, o jẹ nkan pataki ti ilu ti o ba fẹ gba Ominira ni lati kọkọ ni, nitoripe on ni gbogbo enia yio fi mọ wipe ilu na ti di Ominira.

Nitorina a wa Oniwe Irohin Imọlẹ fi gbogbo ọkan wa bẹ ẹnyin enia Naijiria, lọmọde, lagba, lọkunrin ati lobinrin pe, ki ẹ jẹki a bọwọ fun orin Orilẹ ede wa yi, papa lasiko ti awọn ọpọlọpọ alejo lati ilu okere kun ilu wa yi, ẹ ma ṣe jẹki awọn Oyinbo Gẹsi ti a gba Ominira lọwọ wọn ma da hẹ! wa, ẹ maṣe jẹ ki a doju ti ilu wa o.

Papa ẹnyin ti ẹ nlọ woran ere alalẹ a bẹ yin, nigbati wọn ba ti pari ere yi tan, ẹ jọwọ, ẹ ni suru duro tọwọtọwọ nigbati wọn ba nkọ orin Orilẹ ede wa lọwọ, ẹ jẹ ki a gbe ilu wa ga nipa pe ki a ma ṣe ohun ti a ba ri pe o tọ si awa enia Naijiria gẹgẹ bi, bi bọwọ fun orin Orilẹ ede wa, ẹ ma ṣe doju ti ilu wa loju orisirisi awọn ajeji ti o nwọ ilu lojojumọ lati wa wo ilọsiwaju ati awọn enia Naijiria.

## Olotu Daily Times joye titun ni Ijebu Ijesha



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbẹni Theophilus Ọla ti iṣe Olotu iwe Irohin Daily Times ti ẹ ka Ibadan, ni wọn fi jẹ Oye Oyesuwọn ti ilu Ijẹbu Ijẹsha, eniti a nwo ti o fi rukẹrẹ le lori ni Ọba Arojojoye keji Ọba Ijẹbu Ijẹsha.

## Awon Idile meji ba ara won ja ijagboro ni Ilu Oka

Irohin ti a gbọ ni wipe Ijagboro bẹ silẹ larin awọn Idile meji wọnyi Aṣina ati Apo lori oro ilẹ ko ṣe ilẹ, Ija na si pọ jọjọ to bẹ ti Ijọba Ibilẹ Ọka fi nkigbe gbami-gba mi lọ si ọdọ awọn Ọlọpa ni Ọka ati Onitsha.

Ninu rogbodiyan na, nwọn lu enikan pa bamu bamu, iwọn ọgọrun enia si fi ara gbalamọ gbogbo awọn ti nwọn fi ara gbalamẹ ni nwọn gbabusun fun ninu ile iwosan nigboro ilu Onitsha fun iwosan, ṣugbọn enia mọkanla ninu awọn enia to fara gba lamo yi wa ninu roju jẹ ati rojumu.

Larin Ija yi, awọn Obinrin ṣigun ọwọ abara le Ọga Ọlọpa kan, bi o ba jẹ wipe nwọn ri aiye gbe ọwọ na wa silẹ ni, ha! nkan iba ṣe. Ohun ti a gbọ wipe o da Ijagboro na silẹ ni ẹni kini gba ilẹ ọn keji

Titi di bi a ti nwi yi, awọn Ọlọpa ko ti ri ẹniti o jẹbi ninu awọn enia na.

## Enia meji mbe lori Roju-je ati Rojumu

Agbọ Irohin wipe awọn Obinrin meji kan lo nrin pade agbako loju ọna. Agbọ wipe bi nwọn ti nrin lọ loju ọna Ikorodu, ni ọkurin Ọdẹlẹsurin kan ba kọlu wọn, o si ṣe wọn leṣe tobẹ gẹ ti o fi jẹ wipe, nṣe ni awọn Ọlọpa gbe awọn enia mejeji nwọnyi lo si Ile Atalsan nibiti nwọn ti nto Egungbo ara enia ti o ba ṣẹ tabi bi enia ba fi ara rọ.

Nigbati awọn Oniwe Irohin lọ sile Iwosan lati bere bi awọn enia na ti wa si, nwọn sọ fun wọn pe ko si ẹniti o le sọ ohun pataki nipa awọn obinrin meji na, ṣugbọn iba ohun ti a mọ nisisiyi ni wipe nwọn nbẹ larin Iye ati Iku.

Nisisiyi awọn enia meji na mbẹ ninu roju jẹ rọjumu ati pẹlu nwọn koiti le daruko awọn ẹni meji na fun aiye gbọ.

## Hu-u - haha! E suru kuru,

OBERẸ LATI OJU EWE KINI

Bi awọn enia ba pe Ẹyọ kan ti nwọn si tẹ ọwọ si wipe ki o wa ṣe Ikaro Ọpa Mbata ọwọ rọ fun wọn, Bayi ni Ẹyọ na yio ṣe, yio fi ẹsẹ kan kunlẹ, yio ma fi idi Ọpa Mbata rẹ kanlẹ, yio fi ori Ọpa na kan ọwọ ti nwọn na si bayi wipe:- Eyi A to-o, Eyi Amolọwọ-ọ eyi Amolẹsẹ-ẹ, eyi afsiku ṣe baba iwa eyi Amọ-timọ-timọ! Hu u H a H a yio to dide yio si rọra fi Ọpa Mbata kan le ẹniti o dawo na.

Emi AFILAKA IGA ẸYỌ ILADO

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## AKA RERIN

LATI ỌWỌ:— ABDULLAHI AWẸLẸNJẸ
NO. 1, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Mo fẹ ṣe ọjọ Ibi mi lọjọ kan, mo si pe gbogbo awọn friends mi, Iyawo mi Asakẹ p a p a na si pe gbogbo awọn frieads rẹ, ni wọn ba ṣe adura larọ, nigbati o si di irọlẹ ni a ba bẹrẹ si i j o recording si nsiṣẹ lọ ran-gbanjan, ti awa ati awọn ọrẹ wa si nmu ọti lọ bi roko-so, nigbati o fi ma to akan bi 8'Oclock ni alẹ, oju mi ti nkọ sara bi ina, bi ọrẹ mi ti a jijọ ti mu ọti yo ti gba mi leti ti emi na si dide wipe kin reply. Gbo! ti mo na ọwọ gba eti bayi, eti Asakẹ ni mo gba, Asakẹ si ti muti yo pupọ, ni o ba gbe chair, o kan wedge rẹ mọ mi lori ni, ko stop rẹ bẹ, ṣe lo tun pa guru simi ti o si bẹrẹ si foju mi stratch ilẹ, ti gbogbo oju mi si bo, awọn ọrẹ mi papa ti muti yo, Ija si di rẹpẹtẹ, ni agbo ba daru, ti a ko si ri a w ọ n oni tape recording mọ. Nwọn ti gbe gone. Bayi ni emi ti mo nyọ ayọ ọjọ Ibi wa di ero Hospital o.

### IDANWO FUN AWA ỌMỌ ẸGBẸ

Awọn arinrin ajo mẹta kan jade nilu wọn, ọkan mu Ẹni kan dani, ko si i b i t i ẹni na ko le gbe enia lọ, ekeji si ni Ado kan, ko si iṣẹ ti a niki o ṣe ti ko niṣe, ẹkẹta si ni Agborun kan, bi a ba ran t a n o le bo to ibusọ kan lero ati ni ibu.

Bi wọn ti nlọ bẹni nwọn pade Ọ d ẹ kan ti o nsure bọ, ti o si duro wi fun w ọ n wipe ilu ti wọn nlọ ni, ojo kan yio rọ nibẹ ati wipe ojo ina ni o j o na, bi o ba kan enia yio pa ni. Bi nwọn ti de ibẹ ojo yi bẹ-rẹ, bẹni Alagborun (Humbreller) na ba ta agborun rẹ, nwọn si lọ lalafia, nigbati o ṣe nwọn de ibi odo nla kan ti o to bi, ni Alado ba la tirẹ mọlẹ ti afara (Bridge) si de, ni wọn ba kọja. Nigbati wọn tun nlọ ni w ọ n ba de ilu kan ti ogun ti pọ (War) nwọn nja ogun na fi-kan fikan to jẹ wipe nwọn ko le mọ ajeji, bi w ọ n ti de ibẹ, ni Ẹlẹni (Mat) ba tẹ ẹni silẹ ti wọn si lọ kuro nibẹ lalafia.

IBERE MI NIYI:— Ninu awọn mẹtẹta yi, tani ẹ lero wipe iṣẹ tirẹ yege ju ti o si lagbara ju n i n u gbogbo wọn. Jọwọ tete kọ itumọ tirẹ ransẹ o, Ọlọrun ko ni fi ku ya wa o. Amin. Mo dupẹ lọwọ Olotu.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pa-taki ti a se ni ase pe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun opọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribi ribi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara fun igbona, ikọ, otutu A i p e r i, Osi Ọmọde, jedijedi, kokoro ori Ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan mi-ran bẹbẹ lọ. O nmu ọmọde ko ma nsun fọnfọn O mu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn omode o sinjẹki awọn omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Ẹnyin Abiyamọ, eku afojuba egbegi yi. Arao yio lenpe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko ṣe mani fun awon Ọmode I j a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni le itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re jẹ 2-6d Igo nla jẹ 4 6d

LILO RẸ:— **Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*

A. K KARIMU ANJOLA & BROS

6,' Balogun Street West, 34,Docemu Street
Lagos Nigeria Lagos
Phone 22515 Phone 24247

## Akiyesi fun awon omo egbe

A fi eyi ṣe isileti fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe a nfẹ ọrọ lorisirisi gẹgẹ bi arosọ i t a n, ọrọ ti o pa ni lẹrin, aroye ti o mu ọgbọn wa ni wọn ba, gẹgẹ bi alọ ati ọgbọ ori ni ede Yoruba (Riddles & Jokes) pẹlu ọrọ ti enia meji lese ti yio si pa ni lẹrin bi akarẹrin, nito-ripe fun anfani awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ti o jẹ ala-kikanju ọmọ ni a ṣe fẹ sọ oju ewe ti ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ di oju ewe meji ninu Iwe Irohin Imọlẹ, nitorina ti o ba ni ere ti o dara ti a le kọ niwọn iba ṣoki, ki o kọ ransẹ si akọwe Agba. A o bẹrẹ si ma se eyi l a t i ọsẹ to mbọ lagbara Ọlọrun.

## Igberaga ko dara fun enia

LATI ỌWỌ:— MUKAILA ỌLANIYI
NO. 156, ỌMO ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni ọdun kan, iyan mu pupọ ni ilu Ijapa, ko si iyọ, lati ra ni ọja; ko si oyọ tabi ewe ọ b ẹ miran ni oko gbogbo ilu si kan gbẹnrin-gbẹnrin, oyi nkọ Ọba papa loju fun ebi, a fi Agbigbo nikan ni o nri onjẹ jẹ, o ngun iyan ni akoko, o si nri ẹran ọya jẹ, o nyo, o si nyọkun.

O ya Ijapa l ẹ n u lati ri eyi, o ni on yio fi ọgbọn tan Agbigbo jẹ boya on yio le ri oye ibi ti o ti nri onjẹ jẹ, oko Ilẹkẹ oniyebiye fun, Agbigbo si gba lati mu ija-pa lọ ibẹ, Ijapa fi ida lẹ iye mọ apa, o si pọn mọ Agbigbo lẹhin titi wọn fi de ẹhin okun ti wọn nlọ, Nwọn si ko onjẹ pupọ bọ ibẹ, ṣugbọn nigbati nwọn pada de arin ilu, Ijapa fẹ fi ara han fun awọn enia, ki wọn ba mọ pe on le fo, o kuro lẹhin Agbigbo o si nfẹ fo fun ara rẹ, ṣugbọn ida apa rẹ yọ lẹsẹkanna o si ja fọ bayi ni Ijapa fi igberaga pa ara rẹ.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE
TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ rirun, rukuruku Pipọn tabi rirun, Iakuregbe, Ibara di wiwo ornnkun, owọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara aisan, titobiju, aiko le gbe ara konkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati orṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹ-bidan yi yio wo san lara rẹ ni kia-kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn Oni rọbi rọbi ma ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba a rara o! Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkọ ṣile meji abọ (2/ 6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

# Olorun ki npania Enu ati Ahon lo npa'na

LAYI OWO:- WOLI KOGBERGBE

Mo ki gbogbo ẹnyin olugbọ ọrọ Ọlọrun ni Ejeka sọ ọrọ ẹnu wa, Oluwa korira awọn onisọkuso, nitorina mo bọ yin ẹnikẹni to ba fẹ alafia ati ara lile ko ṣora fun ọrọ ẹnu rẹ, Oni-gbese ni ẹnu, nitorina mase jẹki ẹnu rẹ ati ahọn rẹ da gbese si ọ lọrun.

Mase ba ẹnu rẹ ṣọrọ fara ti iwọ ko ba fẹ jẹ gbese, Enu lo nfa iku Ojiji, ahọn lo nkọ iwe si wahala, ẹsẹ lo mọ ọna ile gbogbo wọn. Enikẹni to ba fẹran ẹnu tobi ahọn rẹ, yio da gbese lairotẹlẹ. Nitorina ṣora ki iwọ ma ba dagbese airo tẹlẹ, ẹnu ati ahọn ni baba Onigbese, Bẹ pẹlu ni ahọn jẹ ẹya kekere, o nfọn-ru ohun nla Wo o Igi nla ti ina kekere sun jona! Ina si ni Ahọn, aiye ẹsẹ si ni arin awọn ẹya ara wa bi ahọn ti nba gbogbo ara jẹ ti o si ntinabọ ipa aipe, Ọrun apadi si ntinabọ on na.



SAMUEL WOLI KOGBEREGBE

Nitori Olukuluku ẹda ẹiyẹ ati ẹranko ati ejo ati ohun ti mbẹ ninu okun ni a ntu loju ti a si ti tu loju lati owọ ẹda enia wa ṣugbọn ahọn ni ẹnikẹni ko le tu loju.

Ohun buburu alaigbọran ni ahọ o kun fun oro Iku ti ipani lara on afi nyin Oluwa ati baba logo on kanna ni a si fi mbu enia ti a da ni aworan Ọlọrun lati ẹnu kanna ni Iyin ati Eebu ti njade. Ẹnyin ara mi ko ma yẹ ki nkan wọnyi nbẹ JAKỌBU ORI 3, ESE 3 TITI 10. gbogbo ẹnyin ọrẹ mi Ha! H!! Ye! Y!! Ile Aiye ṣoro ni gbigbe. Nitorina toju iwa rẹ Eleṣẹ kan koni lọ laijiya. Nitorina ohun ti enia ba ṣe ni yio jere rẹ, ṣugbọn bi ẹnyin ba gbẹn ti ẹ si ni ohun kikoro ati ija ni ọkan yin Ẹmaṣe rere ki ẹ maṣe ṣeke si otitọ ọgbọn nyin ki ṣe eyi ti o gun oke sokalẹ wa

Ṣugbọn ti aiye yi ni ti ara ni, ti ẹmi esu ni Nitori ibiti o wu on ija ba gbe wa, nibẹ ni rudurudu ati Iṣẹ buruku gbogbo gbe wa.

JAKỌBU ORI 3 ESE 14

Mo fẹ ki ẹ mọ wipe ẹpọ enia lo ngbadura ti Ọlọrun ko si gbọ tirẹ. Ẹnyin nbere lọwọ Ọlọrun ẹnyin kosi ri gba, nitori ẹnyin si bere ki ẹnyin ki o le lo fun ifẹkufẹ ara yin.

Ẹnyin panṣaga Ọkunrin ati panṣaga Obirin ẹnyin ko mọ pe ibarẹ aiye, ọta Ọlọrun ni? Nitorina ẹnikẹni ti o ba fẹ lati jẹ ọrẹ aiye yio di ọta Ọlọrun Jakabu ori 4 ẹsẹ 5 Sunmọ Ọlọrun on yio si sunmọ o, nitoripe iwa enia lo mu ni ṣe gbe. Ẹnu eni lo pa ni, ṣora nitoripe Iku ko ina si onibaonujẹ.

# Henderson Olori L. E. D. B. ti jakule Ijoba, ko fe mo

Agbọ irohin wipe Ijọba da Ọgbẹni Henderson ti nse Olori Igbimọ L. E. D. B. duro kuro lẹnu iṣẹ nitori iṣẹkuṣẹ rẹ lirapa owo ti nwọn nsan fun awọn ti Ijọba gba ile wọn, nigboro ilu Eko, nwọn si ti se ipinnu lati si paiya gbogbo awọn iwa ti Ọgbẹni na hu jade fun gbogbo aiye ao si ri ka ninu Iwe Iroh in ti nwọn ba pari Ipade ti nwọn fẹ ṣe ni ọjọ 24th Oṣu Jan. 1962

Ọgbẹni Hendrson bẹrẹ iṣẹ ni L. E. D. B. ni ọdun 1954 ohun ti o fasabab dida duro ti a fẹ daduro ni afọwọra ti o ṣẹlẹ ninu owo ti o nsan fun awọn ti Ijọba gba ilẹ ati ile kuro lori rẹ, ki o wa sọ bawo lo ti ṣe le jẹ bẹ ki Ọgbẹni Henderson ma mọ.

A ko le ṣa le ṣogun nigbo ki Oṣiṣẹ ma mọ. Ile ati ilẹ ti Ọgbẹni Henderson ti gba ni ẹgbẹrun mẹkanla Pọnun. ti a si tun ile ati ilẹ kanna wọn lẹhin ọdun kan rẹ ni ẹgbẹrun mẹkanlelogun ni ohun ti o tu aṣiri apamọwọ ti Ọgbẹni na ti ṣe

Bi ọrọ na ba ti nlọ si ẹ o ma gbọ.

# Awon Gesi fe lati ma lo je Ase loju Sanma



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Richard Thompson ti Ori rẹ pe, ti o fẹ kọ Ile Onjẹ si loju Sanma, gẹgẹbi aworan Ile onjẹ yio ti ri ni, eyiti a nwo ninu aworan yi.

Nigbati o ba di ni Ọdun 1963 ni a o kọ Ile na, yio ga si oke ni Mẹtalelẹgbẹta ẹsẹ on ni yio si ga ju gbogbo awọn Ile ti o ga julọ ni Igboro Ilu London.

# Ajegboro Dagba nki nyin o!

KERE O! KERE O!! Ajẹgboro-dagba di alagogo Ọba loni mo pe gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ ati ẹnyin ti ẹ wa lati idalẹ wa ra ọja nilu Eko, ẹ tẹ ti silẹ ki ẹ gbọ ọrọ mi loni ẹ ṣọra lọdọ awọn ọmọ onibuga eyiti wọn di sinu pepa Irọ ni wọn npa, ọmọ Jaguda ni wọn nṣe, ti ẹ ba tẹle ọrọ mi owurọ yi yio ṣe gbogbo wa ni anfani.

## ẸNYIN ARA ILU EKO Ẹ ṢỌRA YIN LỌDỌ AWỌN ỌMỌ ONITẸTẸ ATI ONIBUGA JANKARA. OLE NI WỌN

Ikede mi na di ori ko dori o di ori awọn ọmọ alainiṣẹ tapa ati awọn alapa ma ṣiṣẹ ti wọn ta buga ati tẹtẹ ti wọn fi pa ọpọlọpọ enia lẹkun, Ni ọjọ aje ọsẹ tokọja nigbati mo nlọ lori Kẹkẹ mi ni ọna idumagbo ni eti Ọja Jankara ni mo ri awọn enia to pa agbo jọ ti wọn si nkigbe pe Ye! Ye! Orire, ni mo ya ṣibẹ nigbati mo de ibẹ mo ri ọkunrin kan ti o jẹ ago ọwọ, ti ekeji si jẹ pọnun kan, nigbati Baba kan ti o wa ra ọja ni Eko ri awọn ti o jẹ yi oju rẹ yan, on na si fun wọn ni Ṣile kan, ni o ba tọwọ bọ inu pali ti wọn gbe mu o fi le ọkunrin ti o fun lowo lọwọ pe ki o ba on ja, bi ọkunrin yi ti ja diẹ o ri ẹ wo, awọn yoku rẹ si kigbe pe Ye! Inu Baba yi dun o lero pe on ti jẹ owo nla, ọkunrin onitẹtẹ yi sọ fun Baba na pe pọnun mẹwa lojẹ nitorina owo rẹ ku pọnun marun ti yio san fun on Inu Baba yi dun o si ko pọun marun le lọwọ, ni o ba ko pepa ti wọn di koriko sinu rẹ fun u, o wipe tọju rẹ dada nitori ki awọn ọmọ Jaguda maṣe gba lọwọ rẹ, bi baba yi ti gba tan o si kuro nibẹ bi o ti rin siwaju diẹ ni o tu, nigbati o tu buledi epini ni o ba ni bẹ, o ba bu si ẹkun, o si sare pada lati wa ba ọkunrin ti o ta fun, ṣugbọn ko ba wọn ni bẹ mọ, gbogbo wọn ti salọ, ni baba ba nsukun kiri, o si wipe o w o ti o ku lọwọ on ti on si fẹ fi ra ọja ni nitori ọna jinjin ni on ti wa ko si owo moto lọwọ on mọ, Baba yi si nsukun kikoro kiri, mo gbọ pe ọpọlọpọ enia ni wọn ti pa ni ẹkun lowurọ ọjọ na ki o to kan Baba yi. Gẹgẹ bi mo tiṣe sọ siwaju, ti ẹ ba ti ri wọn ẹ ma ṣe ya lọdọ wọn mọ, o l e ni wọn. Ara wọn lo njẹ ago ati owo yẹn, ọ k a n na ni gbogbo awọn ti o nkigbe ye! ye! ye! nitori ki ẹ le ta ni wọn ṣe kigbe bayi, buledi epini ni wọn di s i n u gbogbo rẹ, emi Ajẹgborodagba ti ri idi gbogbo wọn, nitorina ẹ ṣọra yin lọdọ wọn o.

Mo fi iwe mi yi kesi awọn Ọlọpa Inu lati ba wa mojuto ọrọ yi, ki wọn si le awọn ọmọ J a g u d a yi kuro nilu fun wa.

# Awon ti o lo be Ile Gesi wo



Awọn ti a nwo nwọyi ni awọn to lọ si Igbimọ gbogbo agbaiye nilu Oyinbo. Orukọ wọn niwọnyi Lati Ọwọ Os.:-]

Ogbẹni I. B. Ibrahim ara Gambia, Z a k i Samuel Akinsanya, Ọba Isara Naijir a, Sir George Erskine ati Iyawo re, Cecilia ara ile Gh na, J. D. Wireko ara ilẹ Ghana, Ọlọla R. Robinson ara ilẹ Gẹsi. Awọn ti o duro lẹhin ni Ibrahim Rahaim ara ilẹ Malay, Malam S. Sagari ara ilẹ Naijiria.

# E jeki ile yin wa ni mimo nitori Imototo lo ogun Ilera ati Alafia

Mo ki gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ kakiri Agbaiye, ẹ ku inawo ọsọsẹ Oluwa yio ma fi ọpọlọpọ rọpo rẹ fun yin o, mo ki Olotu na, ẹ ṣe fun aiye ti ẹ gba mi lati ma ba awọn enia sọrọ nipa I m ọ t o t o, gẹgẹbi emi tiṣe jẹ Onişegun kan nilu Eko, iṣẹ mi ni lati sọ ohun ti o le din awọn ajakalẹ arun ti o kun ode oni ku. Ohun ti o le din ku na ni Imọtoto nipa pe ki a ma tọju ile wa ki a si ma ri pe o wa ni mimọ laiko si idọti kan rara.

LATI ỌWỌ:-

## Oniseaun Irohin Imole

Eyi ni ọ n a ti a le ma gba ṣe itọju ile wa ti yio fi wa ni mimọ, alafia fun enia ninu ile rẹ wa leri onjẹ to dara, Imọtoto, ki a si tẹ le ofin ilera, eyi ni pe ki awọn ile ati onjẹ wa ma wa ni mimọ, Itunu enia ninu ile, wa lọwọ bi Iyawo ile rẹ, ti nṣiṣẹ ati tọju ile ti o ngbe si, ki a ma ra aga, ibusun a t i atupa olowo iyebiye laiko tọju rẹ bi ẹni fi o w o sofo lo jẹ. bi a ba ra orisirisi ohun meremere lati fi ṣe ile ni ẹṣọ ti a ko ba mu oju to tabi ki a ma tọju ile na, asan ni Obinrin ile ni o nmu ile dun, obinrin na ni lati ma sisẹ rẹ ni ọna ti gbogbo e n i a yio ma gbadun ile ibiti wọn ngbe.

Obinrin gbọdọ lo gbogbo asiko rẹ lori onjẹ sise, aṣọ fifọ ati ile titọju fun awọn ọbi rẹ, eyi ni awọn ọmọ ati Ọkọ rẹ, ṣugbọn bi obinrin ba wa ti o ni iwa buruku ti ko si fẹran enia ko ni ile ti o dara ni Ọkọ ati awọn ọmọ ni lati mọ pe ile wọn jẹ ibiti wọn ni l a t i ni alafia ati iranlọwọ nigba gbogbo, ọrọ mi yi jẹ nipa bi a tiṣe ni lati ma tọju ile wa nigba gbogbo, obinrin ile ti o ba dara ti o si nfẹ alafia f u n Ọkọ rẹ, oni lati ma ka ọrọ mi yi ni ọsọsẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ki o si ma tẹle ofin ilera.

Lọsẹ to mbọ ẹ o tu bọ ma ka bi o ti yẹ ki a ṣe ma tọju ile wa ati awa papa alara, nitorina ẹ jọwọ ẹ maṣe alai ma ka Irohin Imọlẹ lọsọsẹ nitori ọrọ nipa imọtoto pataki yi ti emi ọjọgbọn Onisegun Irohin imọlẹ ti bẹrẹ si kọ sinu iwe yi, Ipade wa bi oyin o.



# Igbesi Aiye mi ninu Igbo Ironupiwada (APA 3)

Lati Owo:- TAJUDEEN A. ADEBOUN.
No 49, EGBE IMOLE AIYE

Enyin Olukawe mi losę tokoja mo şo fun y i n pe o o ma gbo itumo oruke Iwin yi ati oro ti e so fun Baba mi asiko na to nisisiyi lati gbo oro na ki efi Etisile o.

IDI TI AFI WIPE IWIN YI NI ONISURUKONIKAMO LAIYE

Nigba atijo awon ode a ma lo se ode ninu Igbo yi bi won ba si de I b e ija ni awon Iwin yoku ma ngbe ko won loju şugbon Iwin yi nikan ni ki nba won ja, sibe ko da, awon yoku ma fi nse yeye ni won asi ma pe ni ole şugbon Onisuru ri ja o sa. Omugo sebi ole ni Onisuru bere Ija tan, awon omugo si bere si wo lule bi Igi gbigbe şugbon bi won ba ja tan imiran ninu won afi apa da imiran ninu won asi fi e s e da, nigbayi ni Iwin ti ko ja yi yio wa ma wi fun won pe se ko tan nidi yin ns, Bi o ba je pe E ni şuru ni enyin ko ni ma kabamo bayi nigbati awon Iwin yoku ri pe otito oro ni Iwin na nso fun won.

Won si woye re fun Iwa ti o nhu yi, Bi won bu koni soro, bi won na ko ni gbin, Nikehin awon iwin asi tun lo be pe ki o jowo ese awon nipa sise eyi awon iwin yoku ba fun ni oruko gbigbe ti o si nje Onisurukonikamolaiye.

ORO TI IWIN YI SO FUN BABA MI NI YI

Iwin yi wi fun baba mi pe, iwo omo enia jowo te ti sile ko gbo oro mi yi dada, Bi o ba si pada de si ile ki ose wasu re fun awon omo araiye o, Bi Iwin yi ti so bayi tan, Baba mi pe Ina Ikoko taba re o si pe mi mo si da lohun o,i mu gege Ikowe re ki osi ma ko oro Iwin yi sile nitori ohun ti aba ko sile ki şegbe bi ose Ogun odun ni bi o b a gbe iwe na wo iwo yio niran eniti oso, Bayi ni Baba mi wi mo si mu gege ikowe mi ati iwe, mo wi fun won pe oya o, Nigbayi ni Iwin na bere oro re, oni iwo omo enia Eniti oruko re nje APEKUNJOYE, inu mi dun pupo lati mo o loni, şugbon Ologbeni jowo lo ko suru mo suru re nitori pe isoro ti mo ą,to sie lekan ija ni o gbe ko mi loju sibesibe bimo ti soro to ni oko da owo tasi re duro afi nisisiyi ti mo fe ba e soro ni o to pa Ina taba re mo be yin gidigidi lo ko suru kan suru re wayi jowo mo wa ba o so eleyi fun awon omo araiye o. Eniti oba gbo ogbo fun ara re.

Bi won ko ba si gba won ko gba fun ara won jowo ba mi se Iwasu re daradara o, Baba mi dupe lowo re osi wi fun po bere oro re asiko nlo, I w i n yi bere oro iso oni Iwo omo Enia jowo ohun ti Suru ba se ti laiye yi ile ni kini na yio gbe nitori Eyi ki owasu fun awon omo araiye pe Suru ti tan ni orile aiye.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJO

# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi allowolowo ba nda o lamu, bisiromobi mba o lokan je, tabi aisisęse lo nyoo lenu, tabi o tile nşişe na owo işe na ko duro lowo re. Tabi awon Omoraiye ko je ki o gbadun igbesi aiye re ni gbogbo ona kona.

Oko rere tabi aya rere lo nje o niya. Tabi amubo oko tabi ti aya, tabi oja ti o nta ko lo dede, tabi ohun miran lo mba o lokan je ni gbogbo ojo.

Mo daju wipe diedie lo koko bere. Ki o si tun ona re se. Kowe pelu Şile Męwa abo (10/6) pelu Sitampu oni toro (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunșe adanwo na lodo:-

AWORAWO
16, MOLEYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA

# Esi Oro Woli Kogberegbe

Lati Owo:- ALUFA HUSAEN MOHAMMAD

Olutu/ Jowo gba mi laye lati so si oro Woli Samuel Kogberegbe ti o so mo awon Imale lara nipa oro elede jije, ninu iwe yin ti ojo kejo osu yi.

Woli Kogberegbe so bayi pe Elede jije kise ese, o ni iro ati eke, ni awon Imale nşe gbogbo nkan ti Olorun da ni o je mimo ati wipe ko to ki o ma ko okan sile lai ni je ninu won, Woli na tun so ninu oro re wipe iwa ki Olorun bukata, kise nkan jije si enu.

Teletele, e m i ki ka oro Woli Kogberegbe ayafi ti ose ti mo so yi na ni mo koko ka, nitoripe emi ma nro pe eniti ko gberegbe ni ni tolo gegebi oruko re ti o nje emi ko tele mo on na gan ni Oga oniregbe pelu iranu bi o ba je wipe woli yi kan nse wasu lori iwa rere gege bi eni Olorun ni, emi koni ba ja si rara, o te enu mo awon Alhaji ti o nmu Oti ati awon Alufa ti o ndi tira ika, iyen ko buru, o fe ko wa ni iwa rere ni yen.

Bakanna si ni awa Imale le toka si awon Woli eke ti o nlo Iyawo oniyawo ya ni eti Okun, eni kan ki ba enia ja si iru w a s u tabi itaji ba wonyi.

Şugbon nigbati enia ba fe şi araiye lona nipa fifi iro bo otito mole gege bi ti baba oniregbe ti o ni on ko gbe iregbe yi eto ni ki a se kilokilo fun ki o ma ę fi iregbe re di araiye lowo Emi ko ni fi alukurani ba woli na soro ki o ma ba rope iro ni mo fi ntan on je nitori ti on ko mo Alukurani şugbon ma kuku fi Bibeli ti o gbogbo na ba o wi, ki aiye si le mo bi oniregbe ko. Ni Deuteronomi 14 : 8, arika bayi pe " Ati Elede nitori ti o la bata ese şugbon ko je apoje, alaimo ni fun yin. enyin ko gbodo je ninu eran won, be li enyin ko gbodo fi owo kan oku re,

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE

BERE OJULOWO EGBOGI WONYI:-

## "Congreve Female Remedy"

Gbogbonse fun Itoju tabi Ajo Obinrin fun Inu rirun Ibadi riro tabi gige nigbakugba, ati orişirişi arun tabi amodi ti o ma nyo Obinrin lenu ni Inu nigbakugba.

## "Collomack"

Egbogi awon Jamani ti o dara julo fun Itanpera, awo ESE lile, Igbado ese ti ki jeki enia le wo bata (Corn-cure) ati orişirişi arun Ese miran pelu ni

## "Mackotal"

Atamatase Egbogi awon Jamani fun orişirişi amodi "ETI" riro tabi didun fun omode ati agbalagba bi o ti wun ki ojo re ti pe to yio şe iwosan re ni kiakia.

## "Meduprival"

Ojulowo egbogi awon ara ilu Tatanbulu fun iwosan ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU Agbari, Igba aiya Ona-ofun, Imu tutu tabi ti o ma nsomi bi ikun nigbakugba, Kelebe ona ofun tabi agbari hiha, amurun ati orişirişi amodi miran gbogbo ti ibere re je otutu. Bere ti Omode tabi ti agbalagba won yato nipa agbara won n io

Bere ni Şobu:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO
ATI NI AWON ŞOBU IBADAN:-
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA

# Baba Onile ati Obirin kan para won nitori Owo Ile

OWO:- Omokunrin kan ti o nję Jimoh Owatowoşe ko Ile kan silu Owo ti o fi Haya, Lojo kan ti o lo gba owo ile yi ariyanjiyan bę silę larin Onile ati okan ninu awon ti o haya Ile nipa Cwo Ile rę.

Nibiti nwon gbe nso oro yi lowo, ibę ni eniti o haya Ile rope Baba Onile na mo mo şe abosi fun on o fa obę oloju meji yo, o si fi gun Onile na, lo ba gbe şi ti o nsalo.

Bi o ti nsalo, agbo wipe opade Obinrin Adelebo kan ti o lo pon Omi, beni o tun gbe obę le ni Igba-Aiya obirin kan ti o nwę ni Baluwę ti o g b o igbe ati ariwo lo se fanlowo ti Owo Olopa fi tę Apania yi.

---

# Omo ilu Saro lo ko ise won-le-wonle nilu Oyinbo



Eniti a nwo ninu Aworan ni Ogbęni ara I l u Şaro kan ti o lo ko işę Wonlę-Wonlę nilu Oyinbo, ti Oruko rę nję Peter Sqiure, on lo mbę lęnu Idanwo F o t o yiya ati Ile Wiwon.

---


## Akiyesi fun eniti o fe ra tabi ta Ile tabi ile nibi gbogbo

Enikeni ti o ba fę ra tabi tita tabi fifi ile ya tabi lati haya gbogbo ile to dara ti o si laye tabi ile işę tabi ilę ti ko poju adota ęsę ni fifę ati ogorun ęsę ni gigun, nihin tabi lohun ati nibi gbogbo, bi Eko, Ebute metta, Apapa, Yaba Suru Lere, New Lagos, ati paapa ni Idi Oro, Mushin laglo Road ati Ikęja tabi nibikiki, Wa ri Ogbęni:-

**J. B. Crownson Odujobi & Sons**

1st floor 16, BA MGBOSE STREET LAGOS

Tabi ki o pe wa lori ęro Isoro No 24318.


# Esi Oro Woli Kogberegbe

Lati Owo:- ALUFA HUSAEN MOHAMMAD

OBERĘ LATI OJU EWE KĘFA

Ni Lifituku 11: 7, bakan na ni o tun wi, Atun ri ni Maku ori 5, ęsę 12 de 13 wipe nigbati Jesu papa le ęmi esu jade ni ara awon alaisan kan ara awon ęlędę ni ole won si eyi fi han pe Jesu papa ko fę ęlędę ni jiję, ani oni Ikorira si won nitori ti Olorun ko osi şe ję eni iparun ni igbęhin, Wo Isaya 66: 17.

Bi Woli Kogberegbe ba mo pe on fę lati ma se wasu lori iwa rere, kio ma se, şugbon ti oba fę lati ma si araiye lona, kio gbe Iregbe rę mo ni Ile ara rę nikan o. Bi ko ba si ti ka BIBELI de ibi ti ajuwe wonyi kio ma se ję ki oju ti on, kio t e t e pada si odo awon asiwaju rę fun Imo Ijinlę.

Mimo lo ni adin ogbon ko gbe o.

---


BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O SESE DE TI WON NPE NI:-

## "DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN AGBALAGBA OKUNRIN GBOGBO




Dynamiren ję Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awon Jamani ti nse wa fun tita ki ogun (War) ti awon Gęsi pęlu won to şęlę. Lęhin igbana a ko ri irufę egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti işę rę si daju bę yen mo ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranşę si awon Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki won şe iwadi awon elegbogi "Dynamiren" bi won ba si mbę laiye. Won si da esi pada wipe won nbę atipe egbogi na ti a nfę lodo won wa pęlu. Eyi mu inu wa dun pupo julo nitoripe awon Onibara wa mo daju wipe kosi aşanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Egbagbeje irufę rę wa kakiri şugbon bi ti eleyi ko Bi arę ara ba mu o, nigbakugba fun wahala tabi işę de ti o ko ba le jeun daradara, tabi ki o ma le sun de won losan tabi loru tabi awon "Işan ara rę gbogbo" ko ba şişę daradara aręE-emi (breath) inu ko ba gunle dara ara to nitoripe işe tabi wahala şişe ko "NJĘ" fun won ailera gbogbo wonyi ti ojo ori rę (age) ba ti koja ogbon o d u n lo si dede adorin tabi jubę lo mo daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfę lati so ara rę di Otun patapata, oju rę a si jolo, ęran ara rę ti o ti hunjo yio bęrę si dan pada. Ara rę y'o ma gbo konkon nigba kugba "Arę" nigbakubga y'o salo patapata pęlu Igbadun ati Alafia yio de si o.

Bere egbogi na ni Şobu awon:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OŞHOGBO.

